Ètò Ìllànà Ìwọ̀n Ìdíyelé owó Ìpele Gúùsù ìkínní (1):

# ÀWỌN ÌGBẸ́JỌ́ GBOGBOGBÒ

Maryland Transportation Authority

MDTA

Afárá Légíọ́nù Amẹ́ríkà I-270 sí I-370




MDTA tún ṣètò ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò láti wá ẹ̀rí gbogbogbò lórí ìdíyelé owó tí a gbèrò fún ìwọ̀n Ìpele Gúùsù Ìkínní (1): Afárá Légíọ́nù Amẹ́ríkà I-270 sí I-370. Àwọn ìgbẹ́jọ́ náà yóò pèsè ànfààní kan láti sọ àsọyé lábẹ́ àṣẹ fún àkọsílẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ tí a sọ ti gbogbogbò tàbí ní ẹ̀rí ẹnìkan sí ẹnìkan tàbí nípasẹ̀ àsọyé tí a kọ sílẹ̀. MTDA yóò pèsè àwọn ọjọ́ àti ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé fún àwọn ìfilọ̀ ọjọ́ iwájú fún àwọn ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò ní orí ayélujára tàbí ojukojú tí yóò wáyé ní sáà àsọyé náà. Máa ṣe àyẹ̀wò òpó ayélujára náà fún àlàyé síwájú si!

Ìforúkọsílẹ̀ láti pèsè ẹ̀rí ní ìgbẹ̀jọ́ gbogbogbò kan yóò ṣí sílẹ̀ lọ́gán tí a bá ti kéde àwọn ọjọ́ ìgbẹ̀jọ́ gbogbogbò náà. Kò ní sí àgbékalẹ̀ ní àkókò àwọn ìgbẹ̀jọ́ gbogbogbò, tí a kò ní fi ààyè sílẹ̀ sí àwọn èsì sí àwọn ìbéèrè. Gbogbo ènìyàn yóò lè tẹ́tí sí àwọn ìgbẹ̀jọ́ náà bí ó ṣe ń wáyé nípasẹ̀ fóònù tàbí nípa wíwò ó bí ó ṣe ń ṣẹlẹ̀ ní **mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting**. GBOGBO ÀWỌN ÀSỌYÉ tí a gbà, bóyá ní ìgbẹ̀jọ́ náà tàbí nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà mìíràn, ni a ó fùn-ún NÍ ÀÀYÈ KANNÁÀ.

# Sáà Àsọyé Gbogbogbò Ti ṣí sílẹ̀ Nísìnyí Títí di Ọjọ́ kejìlá (12) Oṣù kẹjọ!

Gẹ́gẹ́ bí alábàṣiṣẹ́pọ̀ ní Ìpele Ìkínní (1): Ètò Ìtura fún Afárá Légíọ́nù Amẹ́ríkà  I-270 sí I-70, Àṣẹ Ìgbòkègbodò-ọkọ̀ ìlú Maryland [Maryland Transportation Authority (MDTA)] ńgba àwọn àsọyé gbogbogbò gẹ́gẹ́ bíi ìpín ètò ìlànà owó ìdíyelé fún Ìpele Gúùsù Ìkínní (1): Afárá Légíọ́nù Amẹ́ríkà I-270 sí I-370.

**Àwọn ohun-èlò ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò wa ní Yàrá Àlàyé lórí Ayélujára fún àtúnyẹ̀wò àti àsọyé ní mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting.** Pèsè àwọn àsọyé ní ọ̀kan nínú àwọn ọ̀nà wọ̀nyìí ní Ọjọ́bọ̀, Ọjọ̀ kejìlá (12) ọdún 2021 ní aago márùn-ún ìrọ̀lẹ́ láti lè fikún àkọsílẹ̀ lábẹ́ àṣẹ

- Fi fọ́ọ̀mù àsọyé ẹlẹ́rọ kan tí ó wà ní ojú òpó ní **mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting;**
- Sọ fọ́ọ̀mù àsọyé kalẹ̀ kí o sì fi èyí tí a kọ parí ránṣẹ́ sí **ALB270TollSetting@mdta.maryland.gov;**
- Tẹ̀ àsọyé sí ìwé kí o sì fi fọ́ọ̀mù àsọyé tí a kọ parí ránṣẹ́ sí **Ìpele Gúùsù Ìkínní (1): Afárá Légíọ́nù Amẹ́ríkà I-270 sí I-370 Ti Àsọyé Gbogbogbò ti Ìwọ̀n owó ìdíyelé Àṣẹ Ìgbòkègbodò-ọkọ̀ ìlú Maryland 2310 Broening Highway Baltimore, MD 21224;** tàbí
- Pèsè ẹ̀rí nípa pípè wọlé ní **855-701-1977** kí o sì fi ohùn tí a gbà sílẹ̀ kansoso èyítí kò jú ìṣẹ́jú mẹ́ta lọ sílẹ̀.

*Bí o kò bá lè wọlé sí àwọn ohun-èlò lórí ayélujára, tàbí bí o bá nílò àkànṣe ibùgbé lábẹ́ Òfin ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí ó ní Àléébù tàbí nílò àwọn iṣẹ́ ìtúmọ̀ èdè (ní ọ̀fẹ́), jọ̀wọ́ kàn sí Ọ̀ṣìṣẹ́ ti MDTA ní Àkọlé VI ní mdtaeeo@mdta.maryland.gov tàbí ní 410-537-6720.*